# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LA WA

No. 573 TUESDAY APRIL 7, 1964 (2D)


## Ijọba Da Ọga Ọlọpa Kan Duro

IJỌRA:— Ọrọ di pẹẹntuka, nigbat awọn enia kan belu ọlọpanu kan lọrua mọlẹ nigbati ọga Ọlọpa aṣọmọto kan da mọto Takisi duro ti o si gba owo lọwọ onitakisi na, ti Ọlọpanu na fẹ mu Ọlọpa aṣọmọto loju kanna ni opin ọsẹ ti o kọja yi.

Gẹgẹ bi irohin ti oniwe irohin wa kan fun wa, Ọga Ọlọpa aṣọmọto na da mọto takisi kan duro, bi mọto na ti duro, ni onitakisi na ba fun Ọga Ọlọpa aṣọmọta ni owo kan, bi o si ti da owo na sinu apo ni Ọlọpanu kan ti o wa ninu takisi na ba ragabu rẹ.

Ṣugbọn bi o ti mu Ọlọpa na, ni awọn kan ba ragabu Ọlọpanu na pe, ki o tete f Ọga Ọlọpa na silẹ. Agbọ wipe, nwọn lu Ọlọpanu na bi ejo aijẹ tobẹ ti ko le dide.

Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn ba gbe lọ si Ile-Iwosan fun itọju, nibiti o wa titi di bi a ti nkọwe yi.

A gbọ wipe Ijọba ti da Ọga Ọlọpa aṣọmọto na duro lẹnu iṣẹ, nwọn si ti mu awọn ti o lu Ọlọpanu na. A lero pe Ọga Ọlọpa aṣọmọto na yio farahan niwaju adajọ ninu ọsẹ yi.

## Rogbodiyan Bẹsilẹ L'ẹhin Ipade, Ijọba Da Ọga Ile-Ẹkọ Duro

# AWỌN ỌMỌ ILESHA KỌ ẸGBẸ DẸMỌ !

## Awọn Ọlọpa Ragabu Enia Mẹdogun

ILESHA:- Gbogbo enia bẹrẹsi sare Ọlọmọgbọmọ pọn nigbati rogbodiyan nla kan ṣẹlẹ ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni deede agogo marun irọlẹ nigbati Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati olori ẹgbẹ Dẹmọ ati awọn ẹmẹwa rẹ lọ si Ilesha ni arin ọsẹ ti o kọja yi lati lọ fi idi ẹgbẹ Dẹmọ mulẹ ninu ilu na.



Oloye Fani—Kayọde

Irohin fi ye wa wipe nigbati awọn enia de Ilesha ni gbogbo awọn ara ilu ba bẹrẹsi kigbe Ole ! Ole !! Ole !!! le gbogbo awọn enia na lori.

Nigbati awọn enia na de iwaju ile ẹkọ, "Ilesha Grammar School" agbọ wipe awọn ọmọ Ile-ẹkọ na nṣere lọwọ nigbana ni, bi nwọn si ti gburo pe awọn enia na de itosi ni gbogbo wọn ba sare wa si ẹgbẹ ọna lati ri awọn enia na.

Ṣugbọn bi mọto awọn ena na ti de iwaju awọn ọmọ Ile-ẹkọ ti nwọn to si ẹgbẹ ọna na ni nwọn ba nkigbe Ole ! Ole !! Ole !!! le awọn enia na lori ti o fi jẹ wipe gbogbo awọn ara ilu ati awọn enia ti wa ninu ile ariwo awọn ọmọ Ile-ẹkọ na ti nwọn gbọ lo jẹki nwọn o sare jade.

Ṣugbọn awọn enia na ko duro, nigbati awọn ọmọ ile-ẹkọ na nkigbe "Ole ! Ole !! Ole !!!" nṣe ni nwọn nwa mọto wọn lọ jẹẹ jẹẹ titi nwọn fi de ibiti nwọn o ti ba awọn enia sọrọ.

Nigbati Oloye Akintọla fi mba awọn enia na sọrọ, o ṣe alaye pe on ko lero si awọn ọmọ Ile-ẹkọ na pe, nwọn le hu iru iwa ti nwọn hu rara.

### IJIYA ẸṢẸ

O si ṣe afikun ninu ọrọ rẹ pe, Ijọba yio fi ijiya ti o ba tọ jẹ awọn ọmọ Ile ẹkọ Ilesha Grammar School lori iwa janduku ti awọn ọmọ Ile-ẹkọ na hu.

Oloye Akintọla tun sọ fun gbogbo awọn enia na pe; on yio maa ro iru iya ti o tọ lati fi jẹ Oniwasu Akinyemi ti iṣe Ọga Agba Ile-ẹkọ na.

O tun sọ fun gbogbo enia na gbọ wipe, ẹgbẹ Dẹmọ ki iṣe gbẹ ti ẹnikan le fi ọwọ pa ida rẹ loju, o ni ki awọn to da ẹgbẹ na silẹ, gbogbo awọn Ọba ati Ijoye ni nwọn ti sure fun ẹgbẹ na, ti nwọn si ni ọwọ ninu rẹ pẹlu ki awọn to da ẹgbẹ na silẹ.

Oloye Akintọla wa pari ọrọ rẹ pe, "Iṣẹ gbogbo awọn ara ilu ni, lọmọde ati ni agbalagba, ọkunrin ati obinrin lati faramọ ẹgbẹ na ni Ipinlẹ yi.

Ni ipari, Oloye Akintọla rọ gbogbo awọn enia Ilesha lati gba ẹgbẹ titun na tọwọ tẹsẹ, ire ati anfani ti Oloye na ni o ti sọnu ni Ipinlẹ na o le tun pada bọ.

### FANI-KAYỌDE SỌRỌ

Ninu ọrọ ti rẹ, Oloye Rẹmi Fani-Kayọde, Igbakeji Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ṣe alaye pe, iwa ti awọn Ọlọpa hu ni ọjọ na jẹ eyiti o ya gbogbo enia lẹnu, o ni, "Awọn Ọlọpa ko ṣe iṣẹ ti o yẹ ki nwọn o ṣe ni ọjọ na gẹgẹbi iṣẹ"

Oloye na wa kesi gbogbo enia pe ki nwọn o maa wo ohun ti on yio ṣe fun awọn Ọlọpa fun iru iwa ti nwọn hu na.

Siwaju si i, Oloye Fani-Kayọde ṣe ileri pe, on yio kọ awọn Ọlọpa ni ẹkọ, eyiti awọn enia na yio maa gbọ nigbati o ba ya.

Lori ọrọ ti awọn ọmọ Ile-ẹkọ, Oloye Fani-Kayọde ṣe alaye pe, agba iyanu nla ni ohun ti awọn ọmọ Ile ẹkọ ṣe.



Oloye S. L. Akintọla

O wa sọ pe, "iru ohun ti o ṣẹlẹ yi ko jẹ ṣẹlẹ si Alhaji Ahamdu Bello, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni gbogbo irinajo rẹ ni Ipinlẹ Ariwa tabi Dọkita Okpara ti iṣe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria."

Ni ipari ọrọ rẹ, Oloye na ni, "ẹniti o ba nfi abẹ alafẹfẹ ṣere, nfi ina ṣere, oluwarẹ si tun nfi ori ọka họ imu pẹlu, nitoripe, "ẹniti agbọn ba ta, a ta gbe ni,"

Oloye Akintọla ni gbogbo wahala ti on nṣe lati ri wipe iṣọkan wa jakejado Ipinlẹ Iwọ Orun ki iṣe nitori ti on nikan, bikoṣe fun gbogbo awọn ọmọ wa ti nwọn nbọ lẹhin ọla ni ati paapajulọ awọn ọmọ Ile-ẹkọ Ipinlẹ na.

Wo oju ewe kẹfa

# Jẹki Nrọọkan Ma Jẹki Ngarun

MO ki Olotu ati gbogbo awọn alabaşişẹpọ rẹ ku ewu ọdun Ajinde ti Jesu Kristi Oluwa ati gbogbo onkawe wa gbogbo nyin ni mo ki nko ri Olodi kan Adupẹ fun Olotu fun ọpọlọ tutu rẹ Ọlọrun ko ni da ọpọlọ na ru o amin. Ẹ ku iṣẹ ajinde ara yio ma a jẹ. Ẹni pe ki ẹ ma bọ ni ẹ ko ni ba iṣu ọmọ yio jinna fun nyin jẹ Alawarabi yio fi adua si ọrọ nyin asẹ.

## Lati Ọwọ J. Ọla. Wins

Gbogbo iwe ikọkọ ti awọn kan ninu ẹgbẹ ala-akukọ fi kan awọn ọmọ Ibo to wa ninu ẹgbẹ na pe nwọn feran arawọn ju awọn ọmọ Yoruba N.C. N.C. lọ ni arawọn tu sita fun araiye gbọ ninu ọsẹ ti o kọja yi.

Oloye Fani-Kayọde ni ara nkan ti on fi kuro ninu ẹni-esin-ẹni esin N.C.N.C. ni yi Nwọn ko mọ Yoruba to wa ninu ẹgbẹ na ti Ibo ba jẹ Olori ko fun Yoruba to wa labẹ rẹ ni igbega ti o tọ si rara yio wa mu Ibo ọmọ iya rẹ ti aye rẹ kere si ipo agba.

Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn ti da lohun wipe awawi ni ọrọ Oloye Fani-Kayọde, ọrọ rẹ ko ni ẹsẹ nilẹ mọ, ko duro ni bẹ nikan o tun ni nitoripe ẹgbẹ Alakukọ fẹ ba ẹgbẹ Ọlọpẹ ṣepọ, bẹni ẹgbẹ Ọlọpẹ ti fi iya nla jẹ Alakukọ ni Ipinlẹ na.

jẹ ẹnikan ajẹpe Oloye Akintọla ni o nfi iya jẹ Alakukọ.

Loju wa ni Oloye Obafẹmi Awolọwọ yan Oloye Denais Osadebay ni igbakeji alaga ni Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria eyiti ao gbọ



Oloye Okotie-Ẹboh
Omimi — Ẹjọ

### IJIYA

Ko si ojulowo ati ọlọgbọn ọmọ ilu Naijiria ti yio gba ọrọ na gbọ rara. Nitoripe ni ọdun meji sẹhin ni ẹgbẹ Oloye S. L. Akintọla ya ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre ti enia ba nfi iya

iru rẹ ri ni ilẹ Afirika. A nfẹ ki Oloye Rẹmi Fani-Kayọde wa nkan miran wi ako gbọ irọ rẹ rara.

Ọgbeni T. O. S. Benson ni on faramọ ẹgbẹ titun ti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ ni Iwọ-Orun ti Naijiria, inu on ko dun si aṣepọ

Alakukọ ati Ọlọpẹ rara. Otitọ ni wipe ọgbẹni Benson ati Oloye Okotie-Ẹbọh ni nwọn ko je ki ẹgbẹ Alakukọ papọ mọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni joni, ṣe ẹnyin na ri oju aiye. Şugbọn eke ni oju yin ti

Ni ọjọ na awọn Alakukọ ni bi awọn ba le ba ẹgbẹ Afẹnifẹre ṣe pọ, ẹgbẹ Alakukọ yio tan ni Ipinlẹ Iwọ-Orun, şugbọn ti awọn ba le ba ẹgbẹ Olomi N.P.C. ṣepọ nkan yio ṣẹru re fun awọn. Nitoripe Ijọba Ipinlẹ Ariwa o tura, nwọn ki nba enia ja a fi eniti o ba kọja aye rẹ. Iya ko ni je ọmọnkele (N.E.P.U.) awọn, awọn fi ọkan tan Ijọba na,

### ẸGBẸ SAWABA

Ni olukaluku ba nda ọmu iya rẹ gbe, şugbọn ko pẹ ko jinna ifa nsẹ bi alamọrẹ. Njẹ Alakukọ wa tun ku ni ipinlẹ Iwọ-Orun bi? Nje iya ko wa nje awọn ọmọ ẹgbẹ "Sawaba" bi? Ẹjọwọ emi kọ ni nfun nyio ni esi rẹ. Ẹ gbọ itan kekere yi.

Ijapa nsọ ija ti o ba ọrẹ rẹ ja fun ọmọ rẹ agba, omi iwọ ọmọ mi, ẹ ma şe ọlẹ o, e jẹ alakọni enia. Ni ọjọ kan on ati ọrẹ on şe gbolohun aşọ lo ba di ija were ọrẹ on ti gbe on ni ẹsẹ kan soke, ni on ba fi ekeji tiro ni awọn ba nja lọ bi ilẹ bi ẹni were o tun gbe ẹsẹ keji nilẹ.

Ni ijapa ba dakẹ, ko sọrọ ma, ọmọ rẹ ni baba mi e o sọro ma ni,? Ijapa ni nwọn gbe ... ni ẹsẹ mejeji soke, abi o mọ wipe gbii ni ọkan nitorina on ko ni wi gbii, ko ma ye ọ.

Nitorina ẹ o ni gbọ pe, Alakukọ tan ni Iwọ-Orun lẹnu temi bena ni emi ko ni sọ pe iya nje awọn to wa ni Ipinlẹ Ariwa, bi ẹnyin na ba nka iwe irohin, ẹ ma a ka iye ile ti nwọn gba, enia to binu kuro nibẹ.

### ỌDALẸ

Awọn Yoruba ni o ma a nki ọkunrin kan nigbati o ba dabi enipe ọtẹ ko tan ni ile, nwọn a ma ki olori ologun to nje Balogun, nwọn a ni Balogun Dondo nda-

wa "egbirin ọtẹ bi a ti npa ọkan bẹ ni ọkan nru, awọn kan nparọ mọ ara wọn pe awọn Alakukọ ko fi ọmọ Yaruba si ipo nla a fi ọmọ Ibo, ẹ o ri pe awọn to nsọ bayi ko fẹ iṣọkan Naijiria.

Ọjọgbọn S. A. Aluko ni bi nwọn ko ba fi Yoruba si ipo nla o to bẹ, o si ju bẹ lọ, şebi Yoruba ni Oloye Akintọla ti o fi iin aşiwaju rẹ lẹsẹ a bi Yoruba kọ ni Oloye Fani-Kayọde ti o fi da awọn ẹgbẹ Alakukọ? Bi nwọn ti lẹ fẹ fi Yoruba si ipo nla, ẹnyin aşiwaju yi njẹ ẹ ti ba ilẹ jẹ?

Ọmọ oloye ni ọrọ nba wi, ko ma a ye nyin, o ti ye wa dọba, baiye ti jẹ lẹ ri yi o. ki ẹ fi ọrọ yi şe apẹrẹ.

Awọn ti mọnafiki ati ijamba papọ ti nwọn da ẹgbẹ titun miran silẹ ti oruko rẹ nje DẸMỌ tẹlẹtẹlẹ Opipi ni wọn, nwọn di Ẹmọ ki nwọn wọ igbo lọ loku. Bi a wi ti ai wi; nwọn a sọpe nitori ẹgbẹ Alakukọ dapọ mọ ẹgbẹ Ọlọpẹ ni, awa ti ma wipe nkan ti o pa nyin pọ ni yio tu nyin ka.

Loni mokuro ninu ẹgbẹ Ọlọpẹ m o d i Alakukọ



Ọgbẹni T. O. S. Benson

tabi U. P. P. lọla mo tun kuro ninu Alakukọ ati U.P.P. modi Dẹmọ" ẹnyia lana ẹnyin loni bi ẹkun apa ọkọ jẹ. Tani ẹ nse biko şe ara nyin.

### OYE YA YẸYẸ

Lati bi ọdun meji sẹhin ni oye ti ya yẹyẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun ati eniti o tọ si ati ẹniti ko tọ si ni o di Oloye nwọn nfi amugbo ati amu Ogogoro joye nitori ọtẹ.

Wo oju ew karun

BI O BA NI
Iwe—Titẹ
FUN
Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku
ATI
Iwe Igbeyawo
TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE
Modupẹ Printing Press
16 Bamgboşe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985. Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TỌ AFOJUBA
Dan wa wo lẹẹkanşoşo ki o si ri iyatọ

# Tanganyika Fi Ofin De Awọn Ọmọ Ogun Ilẹ Wọn

DAR-ES-SALAAM:— Ile Igbimọ asofin ilẹ Tanganyika ti ṣee lofin lati da kotu kan silẹ ti yio ma gbọ ẹjọ awọn ọmọ ogun tabi ọlọpa ti o ba fẹ fi ọna ipa gba Ijọba ilẹ na.

Ikede ofin titun yi ni a gbọ pe Igbimọ asofin ilẹ Tanganyika ṣe ni ọsẹ ti o kọja yi.

Onirohin wa fi ye wa pe, Ijọba ilẹ Tanganyika ti ṣe agbara lati le ko awọn kan jọ ti nwọn yio wa gẹgẹ bi Oluranlọwọ fun itẹsiwaju ilẹ na, nwọn si gbọdọ mọ pe iṣẹ wọn ki ṣe fun ifasẹhin ilẹ wọn.

Irohin na tun fi ye wa pe ile Igbimọ yi se ofin yi lati le jọpin ohun ti o le ṣẹlẹ ni ọjọ iwaju.

Onirohin wa fi kun pe larin oṣu ti o kọja yi ni diẹ ninu awọn ọmọ ogun ilẹ Tanganyika yi ko ara wọn jọ ti wọn si gba Ijọba lọwọ awọn ti ati dibo yan lati jẹ aṣoju fun wọn.

Ṣugbọn agbọ pe, lai tito ọjọ mẹta ni agbọ pe ẹniti nṣe Olotu Ijọba ilẹ Tanganyika; Ọlọla Nyerere tun pada bọ si ipo rẹ, ti gbogbo nkan si nlọ letoleto.

# Igbimọ Atunto Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

GẸGẸBI ati fi aṣẹ fun mi lati ọdọ awọn Igbimọ atuneto ẹgbẹ Imọlẹ Aiye pe, nwon ti tu ẹgb Imọlẹ Aiye tẹlẹ ka, a si ti tun da omiran silẹ n torina ti o ba ri pe o fẹ jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ tẹ tun yi ki o kọwe si mi ki o si ri pe o wa si Ipade ni ọjọ kọkanla oṣu kẹrin (11/4/64) ni dede agogo mẹta ọsan.

Ẹgbẹ yi yatọ si ti atẹhinwa a si tun ti ni ofin titun miran, Eyi si ni awọn ere ti ẹgbẹ titun na yio ma ṣe:

1. Lati maa kọ awọn ọdọ ilẹ yi ni ọna bi a ti nkọ irohin, itan, ọro sinu iwe Irohin lati ọdọ awọn Ọjọgbọn oniwe Irohin.
2. Ere bi Bọọlu alafẹsẹ gba, Table Tennis, Swimming, Entertainment, Ayo, Iṣẹ, Draft Ludo Picnic ati ọpọlọpọ awọn nkan miran ti ẹo ma a gbọ ni ipade.

Nitorina ti o ba fẹ tun jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ titun yi ki o wa si ipade ni ọjọ 11/4/64 ni nọmba 16, Bamgboṣe St., Lagos, Ao si tun yan awọn alaṣẹ ẹgbẹ titun

Eyi ni orukọ awọn Igbimọ atunto ẹgbẹ Imọlẹ:—

1. J. Ọla. Okunlọla
2. Latifu Babalọla
3. Sedu Olupo
4. Abudulahi Awẹlẹnjẹ
5. Tmothy Akins

Ẹ jọwọ, ẹ tete de ipade o.

# YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan. 21 - Feb. 18) Iwọ yio ri iranlọwọ airotẹlẹ kan gba, Iyẹn ko wipe ki o kuku ju gbogbo ara silẹ gbẹndẹrẹ, Bi o ko ba tọju iṣẹ rẹ, kele gbe ọ tan

PISCES (Feb. 19 - Mar. 20) Ibinu awọn ẹlomiran le ba nkan jẹ fun ọ, ṣa ṣe suru, gbogbo nkan yio si dara fun ọ de ibiti iwọ ko lero.

ARIES (Mar. 21 - April 20) Gbogbo ọna rẹ yio jẹ ire loni, Iwọ yio ri oju rere enia nibi gbogbo, ibagbe rẹ yio dunmọ gbogbo enia. Ohun kan ti o nfẹ yio tẹ ọ lọwọ

TAURUS (April 21 - May 20) Faaji ọjọ oni yio minringindin fun ọ, ṣugbọn maṣe ronu pupọ ọwọ rẹ yio si tẹ ohun kan ti o ti nlepa.

GEMINI (May 21 – June 22) Mu suru jọjọ loni, bi o ba si kọ lati mu suru, iwọ yio padanu pupọ, o si le pa ọ lara. Suru ni ẹbọ rẹ loni.

CANCER (June 23 - July 22) Ohunkohun ti o ba de nṣe ni ki o gba pẹlu suru ki o ma ba di ijọngbọn si ọ lorun. Maṣe fa ijọngbọn.

LEO July 24–Aug 22) Ara re nfẹ itọju ni pataki maṣe jẹ ijẹkujẹ bẹni ki o ma ṣiṣẹ pakanleke, nitori ọrọ enikan ti iwọ yio sọ dara dara, yio mu ọ ṣe orirere

VIRGO Aug 23-Sept 23) Nitori aidara iwa ti o ni, awọn irawọ ọrun yio bi u si ọ diẹ, lọ tun iwa rẹ ṣe ki awọn irawọ ọrun le Ran ọ lọwọ.

LIBRA Sept 24–Oct 23) Nipa ọgbọn ati lakaye ti o ni iwọ yio ṣe orire nibi iṣẹ rẹ, Mu ileri ti o ṣe fun enia ṣẹ, iwọ yio si bọ kuro ninu wahala.

SCORPIO Oct 24–Nov 22) Bọya iwọ ile lọ si irin ajo loni Ẹṣọ di ọwọ rẹ, nipa iwakuwa sa ma ṣe suru nigbagbogbo.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Orisirisi nkan yio ma yọ si ọ, gbidanwo ki o si ma ṣe rere, gbogbo awọn irawọ ọrun yio ma jẹ tirẹ, nwọn o si ma ṣe iranlọwọ fun ọ.

CAPRICORN Dec 23-Jan 20 Ohun ti o ngbero lati ṣe ko ni jẹ bẹ nitoripe iṣoro diẹ yio wa fun ọ Tọju iṣẹ rẹ, maṣe fi ṣere.

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI- Eleyi yatọ patapata si awọn Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọnmọnọ

RICHELET

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO



Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọkuadimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ọjulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun. Jẹdijẹdi Akọ iba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Eṣ Amodi Apo ile itọ, ẹhin didue tabi ibaradi riro pẹlu Egbon RISALETI a ma a pa gbogbi kokoro buruku ti o wa nbo ẹjẹ ara rẹ patapata yio siin ẹjẹ rẹ mo tonitoni pẹ u.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pelu

Bere egbogi nejbina Richelet yi ni ṣọbu awọn Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 573 TUESDAY, APRIL 7, 1964 (2D)

## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọle Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni o ngbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe nte Imọle Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun meje (1957) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn bi o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba,

16, BAMGBOṢE STREET,
PHONE 21985, LAGOS.

# IKEJIANI DA ỌMỌ YORUBA KAN DURO L'ẸNU IṢẸ

IDDO:— Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni irohin kan gbogbo enia wipe, Dokita Okechuku Ikejiani ti iṣe alaga Ile iṣẹ igbokegbodo ọkọ reluwe ti fun Ọgbẹni Modupẹ Alade, ọkan ninu awọn ọmọ Yoruba diẹ ti o wa ni aye Ọga ninu Ile-iṣẹ ọkọ reluwe ni iwe idaduro fun igba diẹ.

Ọgbẹni Modupẹ Alade, jẹ ọkan ninu awọn Yoruba ti o wa ni aye ọga lẹnu iṣẹ wọn, ni opin ọsẹ ti o kọja yi ni awọn alaṣẹ Ile iṣẹ ọkọ reluwe fun un ni iwe wipe awọn ti da a duro fun igba diẹ lẹnu iṣẹ.



Dokita Nnamdi Azikiwe
Olori Apapọ Ijọba Naijiria

A gbọ wipe ohun ti o fa a ti nwọn fi da ọgbẹni Modupẹ Alade duro lẹnu iṣẹ ni wipe, nwọn gbọ ọrọ inu ile iṣẹ wọn ni ode eyiti nwọn lero pe o n lo sọ ọrọ na.

A gbọ wipe ẹnikan ko ni aṣẹ lati sọ ọrọ Ile iṣẹ na fun awọn oniwe irohin lati tẹ jade a fi ọga agba tabi alaga Ile iṣẹ na.

Irohin fi ye wa wipe idaji owo oṣu ni nwọn o ma a fun Ọgbẹni Alade titi gbogbo asiko idaduro.

Ṣugbọn ko pẹ pupọ lẹhinna ti a fi tun gbọ wipe awọn Alaṣẹ ile iṣẹ na ti tun dojuṣọ awọn ọmọ Yoruba marun kan ninu ile iṣẹ na pe, awọn ni ifura si wọn pe nwọn nsọ aṣiri ile iṣẹ na fun oniwe irohin lati ma tẹ jade fun gbogbo araiye gbọ.



Oloye H. O. Davies

Nitorina agbọ wipe nwọn fẹ da awọn ẹni marun na duro laipẹyi. A gbọ wipe awọn ọmọ Yoruba diẹ ni nwọn wa ninu Ile iṣẹ ọkọ reluwe ọmọ Ibo ni gbogbo awọn enia ti wa nibẹ.

Ṣugbọn Oloye H. O. Davies akọwe Agba ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin ti kọwe si Ọlọla Azikiwe Olori Apapọ Ijọba Naijiria lati tete ri si ọrọ na pe ki nwọn o tete pe Ọgbẹni Modupẹ Alade pada si ẹnu iṣẹ.

Oloye H. O. Davies ṣe alaye pe gbogbo ọrọ ti awọn enia ti nsọ lati ọjọ yi wa wipe, awọn ọmọ Ibo ni Dokita Ikejia ni ngba si iṣẹ, ko ya on lẹnu, ṣugbọn kaka ki Ikejiani ki o fi ṣe atunṣe ọrọ na, nṣe ni o tun nda ọmọ Yoruba duro.

Oloye Davies wa kesi Azikiwe ati Balẹwa pe ki nwọn tete mojuto ọran na, ki Ikejiani o ma si ṣe da awọn ọmọ Yoruba duro mọ, ki o ma ba da ọta silẹ larin awọn ọmọ Yoruba ati Ibo.

Oloye Davies ni ohun ti Ikejiani fẹ ma a ṣe yi, le ba iṣọkan orilẹ-ede yi jẹ.

## Awọn Ọmọ Ilesha Kọ Ẹgbẹ Dẹmọ

Lati Oju Ewe Kini

Ṣugbọn lẹhin ti awọn enia na ti tuka kuro ninu Gbọngan Obokun — Busi, tan, ti Oloye Akintọla ati Oloye Fani-Kayọde ti lọ tan, ni ariwo nla ta, ti gbogbo ilu si nho yungba.

Lẹsẹkẹsẹ nigbogbo awọn ero ọja ba tuka nigbati ariwo de ọdọ wọn ti awọn enia na si bẹrẹsi na ara wọn bi igbati nwọn ba nlu Gudasi.

Ko pẹ Lẹhinna ni awọn mọto nla kan ba ko awọn Ọlọpa de, ti nwọn si tu awọn enia na ka.

Irohin awọn Ọlọpa fi ye wa wipe, gbogbo awọn ile ti o wa ni opopo na ni awọn enia na baje patapata.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn ọlọpa na ba mu awọn enia mẹdogun, enia mẹta ni o si fi ara gba ọgbẹ ṣugbọn awọn ọlọpa ti gbe awọn enia na lọ si Ile Iwoṣan "Wesley Guild Hospital" fun itọju.

Irohin awọn ọlọpa fi ye wa wipe, obinrin kan ti o gbe ọmọ rẹ lọwọ Iyaafin Rosa David ati ọmọ re wa ni Ile-iwosan nisisiyi,

A gbọ wipe ọbẹ, ada aake akifọ-igo ni awọn enia na fi nba ara wọn ja ti nwọn si ngun ara wọn ni ọbẹ ki awọn ọlọpa to da wọn duro.

Irohin kan fi ye wipe Ẹni ọwọ Akinyẹmi ko si ni ile iwe na nigbati iṣẹlẹ na ṣẹlẹ nitoripe o wa ni Eko nibiti o gbe nṣe ipade ninu Ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria.

Ṣugbọn Ikede Ijọba ti o jade ni Ibadan lana fi ye wa pe Ijọba ti da oniwasu Akinyẹmi duro nitori iwa ti awọn ọmọ Ile ẹkọ na hu.

Nigbati oniwe irohin kan lọ bere ọrọ ni ọdọ Ẹnilọwọ Akinyẹmi lana, o ṣe alaye wipe on ko ni ọrọ ti on yio sọ nisisiyi, ṣugbọn on yio ba ipade awọn oniwe irohin sọrọ nigbati on ba ṣe ipade pẹlu awọn igbimọ Ile-ẹkọ na, ti on ba si mọ ero wọn lori ọran na tan.

Oloye Akintọla ati awọn ẹmẹwa rẹ ti kuro ni Ilesha, nwọn si lọ ti lọ si Akurẹ.

A gbọ wipe Ijọba yio ti Ile-ẹkọ na fun igba diẹ na, a si lero pe awọn enia ti awọn Ọlọpa mu yio fara han niwaju adajọ ni owurọ yi.

Bi nwọn ba ti pari ọrọ na si, ẹ o ma a gbọ o.

Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street, Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S. Grammar School) P. O. Box Bariga (7/4/64)